# AWORAN AWỌN OHUN TI ỌRUN
## Heberu 9: 6-28
## ẸKỌ 440 -- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: “A si ti fi lelẹ fun gbogbo enia lati kú lẹ́kanṣoṣo, ṣugbọn lẹhin eyi idajọ” (Heberu 9:27).**

### Agọ

Agọ, ti i ṣe ile isin fun awọn Ọmọ Israeli ni gbogbo ọdun ti wọn fi n rin kiri ninu aginju, jẹ iru agọ ti o ṣe e ka ti o si ṣe e ru lọ si ibikibi ti awọn Ọmọ Israẹli ba n lọ. Nigbakigba ti a ba gbe e kalẹ, ọwọn awọsanma a maa wà ni ori rẹ̀ ni ọsan, ati ọwọn ina ni alẹ, eyi ti o n fi han awọn eniyan naa pe Ọlọrun wà pẹlu wọn.

Agọ naa gun ni ẹsẹ marun-din-ni-aadọta, o si fẹ ni iwọn ẹsẹ mẹẹdogun, a si pin in si ipa meji. Ipa kinni ni a n pe ni Ibi Mimọ, o si gun ni iwọn ọgbọn ẹsẹ, fifẹ rẹ̀ si jẹ ẹsẹ mẹẹdogun. Nibẹ ni pẹpẹ wura wa, tabili akara ifihan, ati fitila wura. Nihin ni awọn alufa a maa ṣe iṣẹ-alufa wọn nigbakigba ti o ba ka ẹni kọọkan wọn.

Aṣọ ikele nla kan ti o nipọn ni o pin Ibi Mimọ niya pẹlu Ibi Mimọ Julọ (a tun maa n pe e ni Mimọ ninu Awọn Mimọ). Ibi Mimọ Julọ jẹ iwọn ẹsẹ mẹẹdogun ni iha rẹ̀ mẹrẹẹrin, o si ga soke ni ẹsẹ mẹẹdogun. Ninu rẹ̀ ni Apoti Ẹri wa. Apoti yi jẹ ti igi ti a fi wura bo ni ori, ninu rẹ̀ ni walaa okuta meji ti a kọ Ofin Mẹwa si lara wa. Ninu apoti yi kan naa ni ikoko manna wa, iru ounjẹ ti awọn Ọmọ Israẹli jẹ fun ogoji ọdun ti wọn gbe ni aginju; ati ọpa Aaroni ti o rudi ti o yọ itanna, ti o tilẹ so eso. Ọlọrun ṣe iṣẹ iyanu yi lati fi han fun awọn eniyan naa pe ọun ti yan Aarọni, lati jẹ alufa ninu Agọ naa, ki i si ṣe awọn olori ẹya mejila ni Oun yan. Awọn Kerubu meji ti a fi wura ṣe n boju wolẹ wo Itẹ Aanu, eyi ti i ṣe ibori fun Apoti Ẹri. Olori alufa nikan ni o le wọ Ibi Mimọ Julọ yi ni kiki Ọjọ Etutu.

### Ọjọ Etutu

Ọjọ Etutu jẹ ọjọ iyasọtọ pataki fun awọn Ju ninu eyi ti wọn ki i ṣe iṣẹ. Ọlọrun ya a sọtọ ni akoko Majẹmu Laelae nigba ti a fun wọn ni Ofin. Wọn gbọdọ maa pa a mọ lẹẹkan lọdun, nigba ti ọdun ba n lọ si opin. O jẹ ọjọ ti awọn eniyan ni lati ronupiwada ohunkohun ti wọn ti ṣe lodi leerin ọdun ti o kọja. Wọn ni lati kaanu fun awọn ẹsẹ wọn. “On o jẹ́ ọjọ́ isimi fun nyin, ki ẹnyin ki o si pọ́n ọkannyin loju”(Lefitiku 16:31). Wọn ni lati fi ọpọlọpọ ẹran ṣe irubọ ni ọjọ naa yatọsi ọrẹ ẹbọ sisun ti wọn n ṣe lati igba de igba. Awọn alufa paapaa tilẹ ni lati kọ ṣe irubọ fun ara wọn ná, lati ri i daju pe wọn wa ni mimọ́, wọn si yẹ fun iṣẹ wọn.

“Laisi itajẹsilẹ kò si idariji” (Heberu 9:22). Lati ibẹrẹ ọjọ iwa ẹjẹ ni a maa n ta silẹ fun ifiji (idariji) ẹṣẹ. Nigbooṣe Jesu paapaa wa lati ta Ẹjẹ Rẹ̀ silẹ ki a le gba gbogbo eniyan la: ṣugbọn ṣiwaju akoko wiwa Rẹ̀, nigba ti gbogbo aye ṣI n foju sọna fun wiwa Rẹ̀, ọpọlọpọ ẹran ni wọn maa n pa lati mu Ofin ṣẹ. Gbogbo ẹjẹ (ẹran) ti a t ta silẹ nigbogbo ọgọrun ọdun wọnni jẹ apẹẹrẹ Ẹjẹ Jesu, wọn si n tọka si Jesu.

Nitori eyi, ni Ọjọ Etutu, bi awọn eniyan ti n kannu fun ẹṣẹ wọn a gbọdọ ta ẹjẹ silẹ lati kọkọ ya awọn alufa si mimọ ati lẹhin naa fun gbogbo eniyan. Kikaanu lasan nikan ko to. Olori alufa a maa mu ẹjẹ naa wọ ịbi Mimọlọ a si fi wọn Pẹpẹ Wura, lẹhin naa a mu un lọ si Ibi Mimọ Julọ a si fi wọn Itẹ Aanu fun gbogbo eniyan. Eyi yi pẹlu jẹ apẹẹrẹ ohun ti o dara ju bee lọti o ṣI n bọ wa, nigba ti Jesu yoo wa si aye ti  ti yoo si jẹ “ẹbọ ti o san ju, “yoo si wọ Ọrun lọ, ti I ṣe Agọ “ti o san jụ̀”.

Awọn ẹbọ miiran wa ti wọn maa n jẹ nibi Agọ: awọn miran si jẹ ti ohun mimu, ti wọn maa n mu gẹgẹ bi niwaju Oluwa. Gbogbo nkan wọnyi n mu Ofin ṣẹ ni, “titi fi di igba atunsẹ” nigba ti Jesu yoo de, ṣugbọn wọn ko le “wẹ ẹri ọkan mọ” afi ti awọn eniyan ti wọn ẹbọ naa wa ba le fi igbagbọ wo ọjọ iwaju ki wọn si ri Jesu ninu ẹbọ wọnyi.

Nigba ti Jesu de, ki i ṣe kiki pe O jẹ Olori Alufa nikan ṣugbọn O ta Ẹjẹ Oun tikara Rẹ̀ silẹ. Ẹjẹ Rẹ̀ le ṣe etutu ti o san ju ti akọ malu ati ti ewurẹ lọ. Nigba ti a ba ronupiwada, ti a ba kaanu fun ẹṣẹ wa, ti a si gbadura si Jesu fun idariji ẹṣẹ, Ẹjẹ Rẹ̀ a si wẹ ẹṣẹ nù. Nipa Ẹjẹ Rẹ̀ a ni agbara lati bori ẹṣẹ -- itumọ eyi ni pe a le wa layé lai tun da ẹṣẹ mọ. Paulu sọ fun ni pe Ẹjẹ Jesu maa n wẹ ni mọ kuro ninu “oku iṣẹ” itumọ eyi ni pe awọn eniyan ko tun ṣẹṣẹ n lati na fi ẹran rubọ mọ.

### Sisin ninu Ẹmi

Jesu sọ fun obinrin ni ni ibi kanga pe: “Wakati mbọ, o si de tan nisisiyi, nigbati awọn olusin tõtọ yio mã sin Baba li ẹmi ati li otitọ: nitori irù wọn ni Baba nwá ki o ma sin on” (Johannu 4:23). Iru ọnati a gbọdọ gba fi sin Jesu niyi: a o maa gbadura si I, a o fi ayé wa fun Un, a o fi ifẹ ọkan wa lelẹ fun ụn, a o gba A gbọ. Nigba ti Oun ba dahun adura wa, “Ẹmi tikararẹ̀ li o mba ẹmi wa jẹri pe, ọmọ Ọlọrun li awa iṣe”(Romu 8:16). A maa n mọ nigba ti a ba tun wa bi. A maa n mọ nigba ti a ba sọ wa di mimọ, ati nigbati a ba fi Ẹmi Mimọ wọ ni. Ni ọpọlọpọ igba

miran Ọlọrun maa n fun wa ni ẹri ti o dajuni idahunsi adura wa. Olugbala ti O wà laaye ni tootọ ni a n sin Ẹni ti O si n fẹ ṣe ohun rere gbogbo fun awọn ọmọ Rẹ̀.

**Alagbawi Naa**

Nigba ti Ọlọrun fi Ofin le Mose lọwọ fun awọn Ọmọ Israẹli, Mose jẹ alagbawi – o jẹ alarina laarin Ọlọrun ati eniyan. Ọlọrun sọ fun Mose ohun ti yoo sọ fun awọn Ọmọ Israẹli; awọn Ọmọ Israẹli si sọ fun ôse ohun ti yoo ba wọn sọ fun Ọlọrun. Ṣugbọn Mose sọ fun wọn pe ni ọjọ kan wọn yoo ni alagbawi mira: " **OLUWA** Ọlọrun rẹ yio gbé woli kan dide fun ọ lãrin rẹ̀, ninu awọn arakunrin rẹ̀, bi emi; on ni ki ẹnyin ki o fetisi" (Deuteronomi 18:15). Awọṅ Ju ni akoko ti Kristi wa laye ṣi n fẹ maa "fetisi" Mose, ṣụgbọn Mose tikara rẹ̀ ti wi pe Jesu ni ki wọn fi eti silẹ si. Ojuṣe wa ni ọjọ oni ni lati gbe igbesi-aye wa gẹgẹ bi ofin wọnni ti Jeu gbe kalẹ.

Ọrọ ti a pe ni "majẹmu," gẹgẹ bi a ti lo o ninu ẹkọ yi, tumọ si iwe ihagun. Nigba ti ẹni kan ba ṣẹ iwe iháun, ti o fi ohun ini rẹ̀ silẹ fun ẹbi rẹ̀ tabi awọn miran, a ko le mu iwe yi lo titi ẹni ti o ṣe e yoo fi kú. Jesu ṣe "iwe ogún" Rẹ̀ ani eto Rẹ̀ fun igbala, lẹhin naa O kú lati mu ki eto naa bẹrẹ si i ṣiṣẹ. Nitori pe Jesu kú O si tun jinde, awa le jogun iye ainipẹkun. Ẹjẹ ti O si ta silẹ ni akoko iku Rẹ̀ n wẹ ọkan wa mọ kuro ninu ẹṣẹ O si n mura wa silẹ fun Ọrun.

Gẹgẹ bi apẹẹrẹ iwẹnumọ yi, Mose a maa pa ẹran, a si maa fi ẹjẹ wọn iwe "majẹmu kinni" tabi Ofin pẹlu. Bakan naa ni oun a maa fi ẹjẹ wọn ara Agọ ti o wa ninu aginju, ati ara awọn eniyan paapaa. Gbogbo iwọnyi jẹ apẹẹrẹ pe ni ọjọ kan a o fi Ẹjẹ Jesu wẹ wa mọ.

Agọ ti a pa ni aginju jẹ aworan Agọ ti oke ọrun. A le fi ẹjẹ malu ati ti ewurẹ ya ọ ti aye si mimọ, ṣugbọn Agọ ti oke ọrun nibi ti Jesu wọ lọ n beere Ẹjẹ ti o san ju bee lọ -- nitori idi eyi Jesu mu Ẹjẹ Oun tikara Rẹ̀ lọwọ nigba ti o wọ inu ọ ti Oke Ọrun lati bẹbẹ fun wa niwaju Ọlọrun. Ẹẹkan ṣoṣo si ti to – Oun ko ṣẹṣẹ ni lati ma ṣe e ni ọdọọdun gẹgẹ bi olori alufa ti maa n ṣe. Ẹẹkan ṣoṣo ni O ṣe e "li opin aiye", eyi ni akoko wiwa Rẹ̀, tabi, gẹgẹ bi a ti kọ ọ silẹ ni ibomiran, "nigbati akokò kìkun na de" (Galatia 4:4). O mu Iwe Mimọ ṣẹ gẹgẹ bi asọtẹlẹ awọn woli.

**Iku Daju**

Ẹsẹ Iwe Mimọ kan wa ti olukuluku eniyan gbagbọ; "A si ti fi lelẹ fun gbogbo enia lati kú lẽkanṣoṣo" (Heberu 9:27). Bi o ti wu ki awọn ọba ati awọn ada-nikan-paṣẹ ti ni agbara to, o pẹ, o ya, wọn yoo ku, ẹlomiran a si gba ipo wọn. Awọn onimọ-ijinlẹ le jafafa pupọ, awọn naa pẹlu gbọdọ kú nigba ti akoko wọn ba to. Awọṅ akọrin ati awọn adanilaraya gbogbo le maa mu inu awọn eniyan dun bẹẹ ni gbogbo ọjọ aye wọṅ, ṣugbọn ẹmi awọn naa yoo wa si opin pẹlu nigbooṣe.

Fun Onigbagbọ, iku jẹ ọna kan lasan si Ilẹ Ti o Dara Ju. Ṣugbọn ẹlẹṣẹ yoo lọ si inu ijiya ayeraye. Olukuluku eniyan, rere tabi buburu, ni a o da lẹjọ lẹyin ti o ba fi aye yi silẹ. "Lẹhin eyi idajọ", jẹ odod Ọrọ Ọlọrun bakan naa bi eyi ti o sọ pe gbogbo eniyan ni lati kú. O ṣe iyebiye pupọ pe a ni lati mura silẹ fun idajọ.

Jesu san gbese fun irapada wa, gbogbo wa ni a si ni anfaani lati ba A gbe titi aye. Bi a ba wa ni imurasilẹ, a o maa fi oju sọna pẹlu itara lati ri I. Oun yoo fun wa ni ara ologo ti a ki yoo danwo mọ lati da ẹṣẹ, tabi ti yoo tun mọ irora tabi ibanujẹ.

## AWỌN IBEERE

1. Bawo ni Agọ ti a pa ni aginju ti tobi to?
2. Ki ni pin Ibi Mimọ Julọ?
3. Ki ni wà ninu Apoti Majẹmu?
4. Ki ni Ọjọ Etutu?
5. Ẹjẹ wo ni Jesu mu lọ si Ọrun nigba ti o gba ipo Alufa?
6. Ki ni Ẹjẹ Jesu le ṣe?
7. Ki ni Jesu sọ fun obinrin ni leti kanga?
8. Ki ni alagbawi jẹ?
9. Tani Mose sọ pe yoo wá gẹgẹ bi alagbawi?
10. Ki ni Majẹmu?
11. Ki ni yoo ṣẹlẹ lẹhin iku?